# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 864 LAGOS SATURDAY APRIL 13— APRIL 19 KOBO MEJI (2D) 1963


# Awon Omo Ile Igbimo Faramo Ijoba Akintola

IBADAN—Ni ijẹrin ọjọ Iṣẹgun ti nwọn pe gbogbo ijoke awọn ikọ ile Igbimọ Asofin si ni Agodi Ibadan ni Gomina ilu na, Ọlọla Joseph Fadahunsi sọ pato ọrọ fun gbogbo awọn ọmọ oṣelu ti nwọn fi idibo yan si ile Igbimọ Ijọba Iwọ Orun ati awọn ijoye lọba-lọba wipe Ijọba tuntun Ipinlẹ Iwọ Orun na ti ṣe tan lati ṣe nkan ribi-ribi fun awọn ara ilu Nigeria.

Ki nwọn to bẹrẹ ipade ile Igbimọ na Oloye Akintọla, iyawo rẹ ati akọbi ọmọ rẹ ninu mọto kan pẹlu igbakeji rẹ, Ọgbẹni Fani-Kayọde pẹlu ninu

( Wo yoku loju ewe kẹjọ )



Oloye SAMUẸL LALCKE AKINTỌLA, ọmọ Oye, Baba Ogbomọsho, o gba iyi, o si gba ẹyẹ lọwọ awọn Ọba ati Ijoye ti o wa si ile Igbimọ niguati o sọ fun wọn pe awọn yio san gbogbo owo atẹhin wa fun wọn.



Eleyi ni aworan Alhaji Oloye DAUDA S. ADEGBENRO, ọmọ Olowu, ọmọ Ajibọsin, Alhaji Adegbenro tiṣe aṣiwaju awọn ọmọ Afẹnifẹre (A.G.) ninu ile Igbimọ Aṣofin. Alhaji Adegbenro ni o yẹ kiawọn fi aake kọri, awọn ni ko ba nwọn ṣe ipade pajawiri ti nwọn pe ni Ibadan wipe ọna ẹtọ nwọn ko pe e ni.

## Omo Eko Kan Mu Siga De Ogba Ewon Ni Ilu Oyinbo

LONDON—Adajọ Kotu awọn Ọlopa kan ti orukọ rẹ njẹ Cecil Campion sọ ọmọ Eko kan ti orukọ rẹ njẹ Solomon Laguda sẹwọn oṣu mẹta fun siga-igbo ti o nmu ti awọn ọlọpa ba lọwọ rẹ.

Laguda jẹ ọkan ninu awọn ọmọ "Eko-Eroya" ti nwọn ko ri iṣẹ ṣe ni ilu Oyinbo ti nwọn si kọ lati pada wa si ile; gbogbo wọn ni nwọn ma nlọ ṣe.

Gẹgẹbi waya ti a ri gba lati ilu Oyinbo lọdọ baba oniwe irohin wa n pa arẹfin na, Laguda lọ si ile faaji kan ni adugbo kan ni ibi kan ti nwọn npe ni Stepney, o

( Wo yoku loju ewe kẹjọ )

Ofin Ilu:

# Ajele Kan Faramo Oro Adajo Onyeama

PORT-HARCROUT—Ajẹle kan ni ilu Ibo ti orukọ re njẹ Michael Ogon ni on faramọ ọrọ-ẹkọ ti Adajọ-agba, Ọgbẹni Chas Daddy Onyeama sọ fun awọn ọn olewe King's College l'Eko ti o ni o yẹ ki awọn alakoso Ijọba wa ma gba itumọ ti awọn adajọ ba sọ lori awọn ofin ilu ati pe bawo ni agbara Ijọba wa yio ti ri lọwọ awọn enia wa lẹhin ọla, ti awọn oṣelu kan ni ile Igbimọ Apapọṣe l'Eko ni ọrọ na ju ẹnu adajọ yi lọ ati pe ko yẹ ki o sọ nkan ti o wi jade yi ni asiko ti gbogbo awọn Oyinbo nfoju si gbogbo Kotu (ile igbẹjọ) wa lara wipe a ki ṣe idajọ ododo nibẹ; nkan ti awọn oṣelu ba ni ki a da lẹjọ ni a ma nda lẹjọ nigbagbogbo.

Ajẹlẹ Ọgon ni ko yẹ awọn ikọ ti a ran fi idibo sile igbimọ bo adajọ yi lẹnu rara nitori ofin iṣelu wa ko wipe ki a fọwọ bo ẹnikẹni lẹnu lati sọ nkan ti o ro nipa bi a ti nṣelu si. Ọgbẹni Ogon ni gbogbo nkan ti adajọ agba yi sọ ni on faramọ.

O tun ṣe alaye siwaju wipe ni ilu awọn Gẹsi ati awọn Oyinbo Amerika awọn adajọ ti nwọn nṣe idajọ nibẹ nsọ nkan ti o ba wa lọkan ẹnikan ninu awọn oṣelu ko sini bi wọn lere wipe kinni ṣe wọn ti nwọn ti nwọn ṣe sọ bẹ ati pe ki nwọn ko ọrọ na jẹ.

Adajọ Onyeama ni ti a ba nfẹ irọrun ni ilu ti a ko fẹ wahala lẹhin ọla, o yẹ ki a tẹle ilana Ijọba rere ti awọn Gẹsi fi silẹ ti nwọn gbe le wa lọwọ ki nwọn to fun wa ni ominira, ki a ye woju ṣe idajọ ninu gbogbo ile idajọ wa.



Facts speak for themselves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No doubt it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last just as much now as they were then, to give many years and many miles of trouble-free, economical service.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS. (EB). IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT HARCOURT: ABA.

SUB-DISTRIBUTORS

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY. ONITSHA. ABA.

## OLOYE AKINTOLA NI IJỌBA YIO SANWO AWỌN ỌBA

IBADAN— Oloye S.L. Akintọla, Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti awọn ọmọ ile Igbimọ ni awọn

(Wo yeku loju 'ewe keje)

Awon Iwe Asiko:

# Itan Awon Omo (Yoruba) Oduduwa

(LATI ỌWỌ AKỌWE)

Mo ro wipe gbogbo yin ni ẹ ti ṣe akiyesi ẹsẹ ọrọ mi ni ọsọsẹ ti mo fi nṣe ori iwe ti mo nkọ nipa awọn iwe Asiko bayi:EDE YORUBA DUN KA? Nitotọ ede Yoruba dun ka pupọ ṣugbọn ko nṣe ki a ka'we nikan ni o wa ninu iwe kika, bikoṣe ki a tun ri ọgbọn kọ ninu nkan ti a ba ka na.

Eyi mu mi niran igbati emi wa ni ọdọ, ti mo nlọ si ile-ẹkọ pẹlu awọn ọmọ ilẹgbẹ mi, ti oluko wa ba yan ibikan fun wa ninu iwe na wipe ki a ka a, ti a ba si ka a tan, nwọn a ma bi wa lere orişirişi ọrọ lori nkan ti a ka na, eleyi a si ma jẹki a ni imọ kun imọ ati oye kun oye.

Ni ọsẹ yi, itan pataki kan ni mo fẹ mu jade ninu iwe AKỌKA YORUBA (Apa Karun) ti Alufa (Rev.) E.A. Atilade şeşẹ tẹ jade fun awa Yoruba ati awọn ti o fẹ mọ nkan itan ijinlẹ nipa orilẹ awọn ọmọ Yoruba ati ibiti nwọn ti şẹ wa.

Itan na kọ awọn ọmọde ati agbalagba logbọn lori itan abalaiye ti awọn Oyinbo ma npe ni ancient history). Eyiti a ka nipa ti ilu ajoji to,o yẹ ki awa na bẹrẹsi ma tọju itan ilẹ wa. Itan na niyi:

## Awon Omo Oduduwa

Gẹgẹbi itan atọwọdọwọ, Lamurudu in baba nla awọn Yoruba. Lamurudu yi ti Ilẹ Egypt wa si ilu Mecca ni Arabia, o si di ọba ibẹ. Lamurudu bi awọn ọmọ mẹta. Ekini ni Oduduwa; ekeji ni ọba Gogobiri ati ẹkẹta ni ọba Kukawa awọn ilu ti nwọn wa ni apa ilẹ Hausa.

Ija igboro Lẹ silẹ nitori ọran ẹsin ni ilu Mecca ninu eyiti a pa Lamurudu ti a si le awọn ọmọ rẹ jade kuro ni Mecca. Lati Mecca ni Arabia ni awọn si do si ibi kan ti a npe ni Yarba, agbegbe kan ni Gusu ilẹ Egypt. Boya, lati inu oruko yi, Yarba ni a ti mu orukọ ti a npe ni Yoruba jade. Lati ibẹ ni awọn ọmọ Lamurudu ti pinya, ti Oduduwa wa do si Ile-Ifẹ ati ti ọkan ninu awọn aburo re wa do si Gogobiri ati ti ekeji si do si Kukawa ni apa ni Ilẹ Hausa.

Ni Ile-Ifẹ ni Oduduwa ku si, ni ẹ si ni ọmọ re ti a npe ni Ọkanbi ku si pẹlu. Ọkanbi yi bi awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin meje, lara awọn ẹniti gbogbo awọn orişirişi ẹya Yoruba ti şẹ. Ọmọ re akọbi je obirin, on lo si di Iya Ọba Olowu. Ọmọ ekeji jẹ obinrin bakanna, on lo si di Iya Ọba Alaketu. Ọmọ kẹta jẹ ọkunrin, on lo si di Ọba Ilu Benin.

Oruko ọmọ kẹrin ni Ọrangun ti o di Ọba Ila. Orukọ ọmọ karun ni Onisabẹ ti o di Ọba Sabẹ. Orukọ ọmọ kẹfa ni Olupopo ti o di Ọba Popo. Oruko ọmọ keje ti işe abikẹhin wọn ni Ọranyan, ẹniti o di Alafin ni ipo baba wọn ni Ile-Ifẹ. Itan atọwọdọwọ yi tun sọ pe Alake ti Abẹokuta, Ọwa ti Ilesha ati Alafin ti Ọyọ jẹ awọn ọmọ tabi ọmọ-ọmọ ti Ọranyan.

Ni ijẹri si otitọ ti o wa ninu itan yi; bi a ba fi ẹnikan jẹ oye eyikeyi ninu awọn ọba wọnyi, a ni lati gbe ida Ọranyan wa lati Ile-Ifẹ lati gbe e le e lọwọ ki o to le di alaşẹ bi ọba. Nigbati ijọba Ọranyan ti fi idi mulẹ dada ni Ile-Ifẹ, o pe awọn arakunrin rẹ, awọn ọba Yoruba yoku jọ pe ki nwọn jẹki awọn lọ gbẹsan lara awọn ara ilu Mecca, awọn ẹniti nwọn pa Lamurudu, baba nla wọn. Gbogbo awọn arakunrin rẹ lo jẹ ipe na.

(Wo iyoku ni oju ewe kẹfa)

## Awon Ero Meka Ti Ngbera Diedie

EKO — Ọpọlọpọ awọn ero ti nwọn nfẹ lọ si Mẹka ni ọdun ni ti ngbera diẹ diẹ lati ma lọ. Awọn bi irinwo enia lokunrin ati lobinrin ni nwọn kọ gbera ni Kano ni ijọsan ọjọ Jimọ, Ọba Kano tuntun ti nwọn şẹşẹ yan, Alhaji Mohammadu Inuwa, si gbadura fun gbogbo wọn nidi ọkọ ofurufu (aeroplane) ki nwọn to gbera irin ajo na.

## Oba Meka

Ọba ilu Mẹka paapa şẹşẹ ti irin ajo kan de ni ijẹjọ si ilu ni. Irohin ti a gbọ ni wipe on ati awọn ọmọ amugbalẹhin rẹ ti şe faaji lọ si ilu awọn Oyinbo Faranse. Ninu ile ero ti o wọ si gbogbo awọn oşişẹ ibẹ ti o fo,u kan an ni o fun ni ẹbun agogo ifibọ apo oni wura (Gold watch) kọkan.

Orirohin wa ni Kano ni awọn ko mọ bi Ọba Kano, Alhaji Sanusi, ti nwọn şẹşẹ wa lọ si Azare ni Bauchi a le lọ si Mẹka ti ọdun yi mọ nitoripe o ti gba iwe-ọkọ, o si ti kọ namba ki rogbodiyan ti o de

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

## Awon Ara Ilu Togo Mura Idibo

LOME-Awọn ara ilu Togo nibiti awọn ọlọtẹ kan ti pa Dokita Olympio, alakoso ilu wọn ninu ọdun yi, nmura lọwọ lati şe ipalẹmọ idibo fun Ijọba tuntun nitoripe ede aiyede wa ninu Ijọba pajawiri ti o wa ni ilu na nisisiyi.

Ninu awọn ara ilu na lọkunrin ati lobinrin nşe eyi lọwọ ni awọn ẹgbẹ oşelu kan ni Lome ri iwe ikilọ pataki kan gba lati ilu Saro (Sierra Leone) lọdọ awọn ọmọ ilu Togo ti nwọn fi igba kan sa kuro nilu nitori Ọgbẹni Nicholas Gruntzky ti o fi igba kan şe alakoso ilu na, ti o si nlo awọn enia rẹ ni ilokulo.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)



Aworan yi ni ti Ọlọla Julian Amery, Minista Alabojuto Eto Ọkọ Ofurufu fun Ijọba Ilu Gẹsi. Ọmọ ọdun mẹrinlelogoji ni, o si ti fi igba kan şe işẹ oniwe irohin ri ninu ogun.

# ELETI—OFE

A NJUWKO ŞE WI LEJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosọkọ Street, Lagos, P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAM "ELETI-OFE" LAGOS Phone 23370
VOL XIV. No 864 SATURDAY APRIL 13 APRIL 19 1963


# Onigbagbo, E Ku Odun !

Gẹgẹbi o ti jẹ aşa awa onirohin Eleti-Ofe lati ma kiʼawọn enia wa ydu o je Kiriyo ni. Ni ale nigbati bi ẹsin ti awọn baba wa, ti nwọn npe ni ORUNMILA—nitoto ORUN-NI-O-MO ENITI-YIO-LA, pe nwọn ku ọdun, a fi ọrọ iwe Olotu wa ti ọsẹ yi ki gbogbo ẹnyin ọmọlẹhin Jesu Krisiti kakiri ile yi pe ẹ ku ODUN AJINDE, ai nde ara yio si ma jẹ fun gbogbo wa—Amin, aşẹ.

Afise akiyesi wipe Isti bi oşu kan sẹhin ni gbogbo ẹnyin onkawe wa ti ẹ jẹ elesin ti Jesu Krisiti na ti nşẹra ro, ti ẹ si ngba awẹ fun iranti iya nla ti awọn ọmọ araiye fi jẹ Krisiti na nigba aiye tirẹ.

## Krisiti Arin Wa

Gbogbo iranti iya ti a nşe fun alaişẹ yi dara pupọ, şugbọn o dabi eyiti o jẹ wipe ero awa ọmọ araiye kuru pupọ. Gbogbo igbati a nro baba nla iya ti awọn ara aiye igbani fi jẹ Krisiti, oju ẹlẹşẹ ati apa'nia ni a fi nwo wọn, o si dabi ẹni wipe ki a ri awọn oninubini na ni ojukoju ki a ju wọn si odo Ọsa tabi ki a yin'bọn fun wọn.

A ko tile fẹ ki ẹnikẹni da orukọ JUDASI ni eti ọdọ wa; a gbagbe wipe gbogbo wa ni Judasi ni aiye isisiyi.

## Ati Judasi

Şe iwọ ti o njẹri eke si arakunrin rẹ ni o fẹ sọ wipe o ki şe Judasi ti ọjọ oni ni tabi iwọ ti o nfi ọrọ buruku ahọn rẹ ba ti ẹnikeji re jẹ? Ọgbeni Judasi papa ko'mọ wipe nkan buruku ni on nşe nigbati o tọ fi Kristi han awọn ti yio pa a

Iwa agabangebe ti o wa ninu Judasi ti ijọsi, o wa ninu ogunlọgọ awa ọmọ araiye loni. Iwa bi o ba a, ki o pa a, bi o ko si ba a, ki o bu u lẹse pọ lọwọ wa lọkunrin ati lobinrin.

## Pelu "Kafiri"

Iwa inunibini na ko nşe lodi awọn elẹsin Krisiti nikan ni o pọ si; bi awọn apa'nia ti şe wa ọgbọn lati fi pa Jesu ni Jerusalem ni ijọsi bẹni awọn kan ti nwọn npe ni "Kafiri" ni ilu Mẹka (Mecca) ati Mẹdina şe inunibini ti wọn'şi Anabi Mohamadu nigbati o gbe ọna igbala tirẹ jade si 'wọn.

Nitotọ, Olotitọ ilu ni awa araiye ma npe ni oşika ilu. Lẹhinti a ba gba awẹ ijiya Jesu tan, ti a fi "FIRIJAN", ẹwa awọn Agudu şinu, ti a fi ẹran ẹlẹdẹ jẹ irẹsi ọdun Ajinde tan, o yẹ ki a wa joko ki a ronu jinna bi ni ojojumọ kọ ni awa na npa Jesu ti a si nşe inunibini si ANABI ti o wa larin wa nisisiyi.

Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi. Ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun !

# Iwe Si Olotu

## Adajo Fi Baba Toko Oku Omo Re Sile Sewon

ABA—Ni ọsẹ ti o kọja yi ni adajọ Kotu awọn ọlọpa ju Akọwe Mọto Akero kan ti orukọ rẹ njẹ Godfrey Banigo sẹwọn oşu mẹta nitoripe o kọ oku ọmọ rẹ silẹ.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lati ọdọ akọwe onirohin wa ni ilu Aba, ọmọbinrin kan ti iyawe ọdaran yi bi fun un ku si inu gọta kan ni Aba, nigbati nwọn gbe oku ọmọ na jade tan nwọn ni ki baba rẹ wa gba oku rẹ ninu ile alaisan (General Hospital) lẹhinti dokita ọba ti yẹ oku na wo tan.

Awọn Ọlọpa ni arufin yi kọ jalẹ lati wa gbe oku ọmọ rẹ na ki o sin. Nwọn ni awọn pe e titi ko dahun, Ijọba ni o si sin oku ọmọ na nigbati o fi oku ọmọ na rare titi ni ile awọn lakulaku ti nwọn gbe e si.

## Ile Ibawi Fun Awon Loya

EKO—Awọn alakoso eto idajọ ododo ti Ijọba Apapọşe ti yan awọn Igbimọ ti yio maşe iwadi awọn Lọya ti o ba şẹ tabi eyiti nwọn ba fi ẹjọ rẹ sun wipe awọn fun un lowo ko si şe işẹ fun awọn tabi awọn Lọya ti o ba hu iwa ti o lodi ni ile ẹjọ.

Ki nwọn to gbe ẹjọ awọn Lọya bẹ de iwaju awọn igbimọ ti yio dajọ fun wọn, nwọn ni awọn igbimọ kan lọtọ ti nwọn npe ni awọn igbimọ iwadi, awọn ọmọ igbimọ yi ni yio sọ bi ọrọ na ba yẹ lati gbe de iwaju awọn igbimọ ti yio şe idajọ lee lori.

Awọn Lọya mẹwa pẹlu awọn ọgaasofin Ipinlẹ mẹtẹta ati ọkan l'Eko ni nwọn ni lati wa nibẹ. Nibi aga ijoko awọn ti nwọn yio şe idajọ, awọn Lọya mẹdogun pẹlu awọn adajọ-agba mẹrin ni nwọn ni lati wa nibẹ.

AYILUKA NI :

## Omo Awe Nse 'Kan

Mo gbọ wipe ọpọlọpọ awọn ọmọ ilu Awẹ (lẹba Ọyọ) ti nwọn wa ni idalẹ kakiri ni nwọn yio pesẹ sile siba-siba loni fun ile-ile Şọşi tuntun awọn ONITẸBỌMI (First Baptist Church) ni Oke-Bode dipo ti atijọ ti nwọn ti kọ sibẹ. Ọkẹ kan-o-le ẹgbẹdọgbọn pọnun (£25,000) kise ọmọde owo-iye ti nwọn fẹ fi kọ Şọşi na niyẹn.

Ọwọ lodi, emi Ayiluka paapa ko ba fi ẹsẹ kan de 'be şugbọn mo mọ wipe awọn enia jankan jankan ọmọ Awẹ bi Balẹ Ilu Awẹ, Oloye Adeshina, alaga Ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ Awẹ, Alufa E. A. Atilade, Dokita J. A. Adegbitẹ, Dokita J. T. Ajao ati awọn bẹẹbẹ ni yio wa nibẹ. Ẹ ku ọdun, ẹ si ku inawo ti Şọşi tuntun na; Oluwa ki o ba wa kọ ile na e—Amin.

(Wo yoka loju ewe karun )



Iwọ
Ki y
latig

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(Lati Owo Ayiluka)

## Bata Takalumi

Mo ki yin, ẹyin ti e nfi suru ka akọkun iwe emi Ayiluka ni ọsọsẹ. Ẹ ku ipalẹmọ Ọdun Ajinde ti Jesu ti o ku ọla yi. Ọlọrun ma jẹ ki a pade agbako iku mọte; ki ọmọ wa tabi ẹnikẹni ninu awọn enia wa ma ba wọn ku sinu Okun tabi Odo Ọsa, Majidun ati Odo Ogun ni ọdun yi. Awọn ti nwọn ba si ṣe fanji lọ si Alalubọsa ni Ibadan ki ori awọn yeye wọn gbe wọn dele ni alafia.

O dabi ẹni wipe ọdọdun ni ọrẹ mi Oloye Festus Okotie-Ebọh, minisita alamojuto eto owo-nina Ijọba Apapọse l'Eko ma nko "wahala" tuntun de. Nigba kan awọn onilu agidigbo fi kọrin wipe Okotie-Eboh ko owo tuntun de; igba kan nwọn ni o tun ko Iso tuntun de. Ọdun yi ọrọ **BATA TAKALUMI** ni o tun ko wa fun wa lati ilu awọn Hausa. O ni eyiti a wọ bata ka-ko ti Oloyinbo yi to.

Mo gbọ wipe "Omimi-Ejo" (oriki Oloye Okotie-Eboh niyẹn) paapa ti nkọle ti awọn Itsekiri yio ma kan bata ta fun un ni Sapẹlẹ ati Warri. Gbogbo wa ni a o ma wọ bata Sardauna ati Okotie-Eboh nisisiyi. Mo gbọ wipe TAKALUMI ati OYOYO ni orukọ ti a o ma pẹ awọn bata Kaduna ati ti Sapẹlẹ.

## Fidi-Bo-Poo

Ọrọ ti owo-bode ti nwọn gbe le bata Oyinbo lori yi jẹki nnire owo-ori ti nwọn bu le akara Oyinbo ti a ma npe ni akara FIDI-BỌ POO ni aiye atijọ. Ti o ba fẹ ra iru awọn akara yi ti nwọn din wa lati Reading tabi Hamburg, ti nwọn to sinu panu daradara wa, o ni lati san owo oju eegun. Nitorina ti o ba pẹ panu-akara ẹnyin iyawo wa feran lati ma fi elubọ tabi gari si ko si mọ-nwọn ti ndin akara fidi-bọ-poo jaburata ni papa ati Ikeja nisisiyi.

## Aso Olowonyo

Emi Ayiluka mọ wipe ko si aṣọ ti o lọ nilẹ fun tita to AṢỌ-OLOWONYO (aṣọ itẹkọ funfun) ni mo wi o; bi nwọn ko ba lo o fun lawani wiwe ni ilu Hausa, nwọn a lo o fun agbada. Nibikibi ni a nlo aṣọ itẹkọ funfun yi fun oku sinsin. Nwọn ti gbe owo le ori awọn aṣọ na ti nwọn nko wa lati ilu Oyinbo ki a ba le ri aye ta eyi ti awọn "aboki" wa nhun jaburata ni Kaduna. Ṣe ẹnyin na wa ri wipe nitotọ ni Oloye Okotie-Ẹbọh ko iso-tun-tun de tabi iru oriki wo ni a le fun ọrọ ti o de'lẹ yi?

## Eja Kano

Boya iyawo rẹ ko ti sọ fun ẹ wipe ki o fi owo kun owo-ọbẹ ti o ba fẹ jẹ ẹja inu agolo (Salmon and Sardine) pelu Salad rẹ ninu ọdun Easter yi nitoripe Oloye Okotie-Ẹboh ti la'gi mọ awọn ẹja ati ẹran inu agolo lori.

O ni bi o ba fẹ ẹlẹdẹ ọlọra, wa ri ra ni Apapa; bi o ba si jẹ aguntan oniyọ ni, o wa ni Maiduguri; ẹja gbigbẹ wa ni Kano; adiẹ ati ẹyin-awo wa ni Sokoto ati Gusau. Oloye Okotie-Ẹbọh ni awọn nkan onjẹ ilẹ yi ni ki ẹnyin iyawo wa ma ṣe agbara lati ra fi se onjẹ fun ọkọ yin. Omimi—Ejo, o ṣe pupọ, owo Abu ni a o fi ṣe Abu ni alejo. O digba o!




"BI IWỌ BA NWÁ ASIKI FUNRA RẸ"

Barclays ti se ọpọlọpọ aworan idaraiya to si wunni lati ma wò ninu sinima, eyiti iwọ papa ti lè ri tẹlẹ. Aworan yi jẹ itan nipa ọdọmọkunrin kan ti baba rẹ nan bade lati lọ wá ọrọ̀ funra rẹ. Bi o ti nlọ lo pade enia meta: Ọkan ninu wọn ni mọto nla ti a



fi nko ẹrù, ekeji jẹ arugbo, ẹkẹta jẹ onisọwọ to l'ọrọ̀. Awọn wọnyi ti nfi gbogbo owo wọn pamọ lọdọ Barclays, wọn si ti lowo pupọ. Wọn da imọran fun wipe ki o lọ si Barclays Bank lati bère ifowopamọ nibẹ.

Gbogbo awọn to wà ninu mọto



...ọ ba nwá asiki funra rẹ bi?

...yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ

...igba dẽgba nile ipamọ owo ti Barclays

Owo rẹ mbẹ labẹ abo lọwọ Barclays. Ki yio sọnu atipe bi o ti npọ̀ nibẹ ni bẹni yio ma lési. Lọ bère nibiẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

BARCLAYS BANK D.C.O.

# Ọmo Oduduawa

(O bẹrẹ lati oju ewe kẹta)

Ki Ọranyan to fi Ile-Ifẹ silẹ, o fi iranṣẹ kan silẹ lati ma bọ awọn orişa baba wọn ati lati ma toju afin. Eleyi ni Ad-mu, ẹniti o wa di babalorişa tabi alufa fun gbogbo Ilẹ Yoruba. Ọranyan ati awọn arakunrin rẹ ko le gba ọna ti Oduduwa ba wa si Ile-Ifẹ, nitoripe awọn erun gba ọna na. Nwọn ni lati gba ọna miran ti nwọn lero pe yio ma ori're wa.

Bi nwọn ti nlọ ni ọna irin ajo wọn, nwọn de ib' kan ti a npe ni Iganga, nibiti ija gbe bẹ silẹ larin wọn lori ọran ikoko ọti. Nibẹ ni nwọn gbe binu si ara wọn, nwọn si pada lẹhin Ọranyan. Ọranyan nikan pinnu lati tẹ siwaju, şugbọn nigbati o de Ilẹ awọn Tapa, nwọn ko jẹki o kọja Odo Oya.

(Iyoku di ọsẹ ti o mbọ)

# Eleti-Ofe D'araba

# Ero Meka

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

ba a. Mo gbọ wipe ti yio ba wọkọ ofurufu, o ni lati gba aye lọwọ awọn alaşẹ ijọba Ariwa ni Kaduna, ko si gbọdọ wọkọ na ni Kano a fi Ikẹja ni Eko.

Ọkọ ti yio si ni ọjọ kẹdogbọn oşu yi ni Ọlọla Ahmadu Bello, Sardauna ilu Sokoto mba lọ si Mẹka pẹlu awọn enia rẹ. Lẹhin ọkọ yi ko tun si omiran ti yio tun lọ si Meka lati ilẹ Nigeria mọ.

Ọpọlọpọ awọn ero Mẹka lati Ajaşẹ (Porto-Novo) ti nwọn fẹ wọkọ ni Eko ni nwọn ti de ilẹ yi, awọn miran si ti wọkọ ni Kutonu (Coutonu).

# Awon Ara Togo

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Ninu iwe-ikilọ na (nwọn tilẹ fi ẹda rẹ ranşẹ si Ọgbẹni Gruntzky) nwọn ni ki awọn ara ilu Togo jọwọ ki nwọn maşe dibo lati yan Ọgbẹni Gruntzky nitoripe Ijọba rẹ ko dara rara. Enia buruku ni, nwọn ni on lo jẹ ki ọpọlọpọ awọn sa kuro nilu ti awọn di alarinkiri.

Nwọn ni awọn fẹ ki awọn ara ilu ro ọrọ na daradara, awọn ko fẹ Oyinbo ki o şe alakoso ilẹ awọn rara. Nwọn ni Ọgbẹni Gruntzky ko le pe ara rẹ ni enia dudu rara nitoripe alawọ-funfun ni.

Ni ọjọ karun oşu ti mbọ ni nwọn fi ọjọ idibo na si.

# Awon Akeko Ile Onje



**Aworan tio wa legbe osi yi ni ti awon omo ilu Nigeria meta lokunrin ati lobinrin ti nwon ran lo si ilu oyinbo lati lo ko ise onje tita nile ero. Ninu aworan ti e nwo yi ni igbati awon oluko won ti nko won lona ti nwon ngba kun eran-pipa ni ilu ti won npe ni Blackpool.**

**Oruko gbogbo won niyi (lati apa osi) Iyaafin Irene Faruku lati Kaduna; Ogbeni Adeiye Ola Odeyoye lati Ibadan ati Ogbeni Akinbiyi Eboda lati Otan-Aiyegbaju leti Oshogbo ni Ipinle Iwo Orun.**

## In Treatment Of Mental Illness

# British Doctor Sees Nigerian Experiment

LONDON—Dr. David Goldberg, medical registered at St. Thomas's Hospital, London, who has just returned from a five-week stay in Nigeria, where he worked as medical officer for Nigeria Airways at Ikeja, has spoken highly of the 'work villages' used by Dr. Thomas Lambo at Aro Hospital, Western Nigeria in the treatment of mental illnesses. Dr. Lambo is Professor of Psychiatry at Ibadan.

"The idea of community care for patients suffering from mental in the 16th century-but the way in which Aro Hospital has actually employed whole villages in help in this work is, I think, unique," he told an L.P.S. correspondent at the weekend.

"The great problem in treating the mentally ill in the traditional sort of mental institution is to prevent the patients losing their pride and sense of individuality. The Aro experiment has I think been very successful in avoiding this. It has enabled the patient to remain in a familiar environment and retain his ties with ordinary life, while undergoing treatment. This is the importance of the experiment which has been pioneered at Aro."

## British Table Tennis Champion Will Visit Nigeria



This flashing forehand stroke will be seen by Nigerians in July when Chester Barnes, Britain's 16-years old table tennis star, visits their country to coach and give exhibitions. This picture shows him in action during the English Open Table Tennis Championships in February. At 14, Chester won the English Closed Table Tennis Championship.

AS FUGITIVE OFFENDER

## Enahoro Must Come Home

LONDON—It is now definite that Chief Anthony Enahoro, Vice president of the Action Group who has been detained in Brixton Prison for the past few months under Fugitive Act must come home to face his trial on charges of treasonable felong since the British House of Commons has rejected his plea for political asylum.

The House of Commons on Wednesday night with as overwhelming Government majority decided that Enahoro should be deported home.

An Opposition motion, "That this House regret the action of Her Majesty's Government in refusing political asylum to Chief Enahoro", was defeated by 274 votes to 218.



**Chief A. Enahoro**

The Government amendment, That this House mindful of Great Britain's tradition of granting political asylum here to persons who might otherwise be exposed to unjust or oppressive to treatment in their own country, is confident of the fair and imepartial administration of justice in Nigeria and upholds the decision of the Secretary of State for the Home Department to return Chief Enahoro to stand his trail there", was accepted by 270 votes to 214—also a majority of 55.

*YOUR SPECIALIST FOR ALL*

BUILDING MATERIALS

**BROSSETTE**

**(NIGERIA) LTD.**

WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA

*At your service*

- STOCK
- SPECIAL ORDERS
- TECHNICAL INFORMATIONS

## Omo Eko Kan Mu Siga

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Ibadun aiye rẹ, ṣugbọn bi o ti bọ sita lati ile faaji na ni ọlọpa gba mu wipe on fẹ yẹ ẹ wo.

Bi awọn ọl.pa na ti yẹ apo rẹ wo nwọn ba ewe taba igbo ti o we si siga ni apo rẹ pẹlu awọn ọta ibọn.

O ni ki nwon jowọ ṣe on ni pele nitoripe on ko ni enia ni ile yi, ewe taba yi si ni on fi ngbera ki on ma bu ronu pupọ

## Awọn Omo Ile Igbimo Faramo Ijoba Akintola

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

mọto ayọkẹlẹ keji bẹrẹsi ki awọn ara ilu Ibadan bi nwọn ti nlo lọwọ lọwọ lọ si ile Igbimọ na ni Agodi.

Eyẹ ẹjọ na pọ pupọ; ko si Ẹnikan ti o wọle igbimọ na ti awọn ọlọpa ko yẹ apo rẹ wo lati mọ nkan ti o mu lọwọ.

Gbara ti gbogbo awọn minisita, Ọba, awọn Oloye ti de ile ni Gomina alara paapa, Ọlọla Joseph Ọdẹleye Fadahunsi ti wọ mọto ayọkẹle de, ti o si yẹ awọn ọlọpa ti nwọn wa ninu ẹwu oye wọn ti awọn to lati ṣe ẹyẹ fun u.

Lẹhin eyi ni gbogbo awọn ikọ ile Igbimọ na to lọwọ-lọwọ wọ ile nibiti Gomina na ti ba wọn sọrọ.

## Moto Akero Pa'nia Ni Ona Gombe

GOMBE—Mọto-akero kan ti o takiti bọ si inu koto ni oru ana ni ọna Gombe pa enia mejila ninu awọn ero ti o nko bọ wa si ilu lati arọko ti o ti mbọ.

A gbọ wipe awọn ti nwọn fara pa ninu ewu jamba mọto akero na to enia mẹsan ti nwọn gbe lọ si ile alaisan ilu Gombe, nwọn si wa ninu ewu bi uwọn yio ku, bi nwọn yio la ni.

## E Ku Ewu Odun Ajinde.

## We wish all our Reads Good Easter.


**LAGOS RACE CLUB**

**EASTER RACE MEETING**

SECOND AND THIRD DAYS

TODAY AND MONDAY

First Race at 3. 30 p.m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets.

1st will be paid £2:10/-, 2nd £1:10/- and 3rd 10/-

COME ONE COME ALL.

Hon. Secretary.
Lagos Race Club.


## Iya Olomomeji Faake kori Pe On Fe Oruka

EKO — Obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ 'Funke Owoladi ti o ti bi ọmọ meji fun bale rẹ fi aake kọri ninu ile awọn olotu- igbeyawo wipe ọkọ on na ko gbọdọ fun ẹnikẹni ni oruka "arede" a fi on nigbati o gbọ wipe Ọgbẹni Lati Owolabi fẹ fun obinrin kan ni oruka arede laipẹ yi.

Gẹgẹbi a ti gbọ irohin na lati ọdọ akọwe onirohin wa ni pe Lati ti gbe Funkẹ ni iyawo ni igbakan o si ti bi ọmọ meji fun-ọkan obinrin ekeji ọkunrin ki nwọn to ba ara wọn ja, Funkẹ si wa lọdọ awọn obi rẹ ni Ibadan nibiti o ti ntọju awọn ọmọ ti o bi fun Lati.

Eko ni Latifu Owolabi ọkọ rẹ wa nibiti o gbe ba wọn ṣe iṣẹ BAWAṢE (contractor) ki o to pade ọmọge kan ti orukọ rẹ njẹ Wosilatu Bashọrun; nwọn si ṣe ndehun lati ṣe iyawo alarinrin ni ọna ti Oloyinbo, ki awọn fun ara wọn ni oruka arede, eleyi ni Funkẹ iyawo akọkọ gbọ ti o fi sare wa lati Ibadan si ile awọn baba eleto igbeyawo wipe ki nwọn jọwọ ki ma ṣe fun ẹnikẹni ni oruka arede a fi on.

## Olopa Aganyin Mu Eniti Ko Korin

ACCRA -- Ni alẹ ana ni ile iṣere kan ni Ghana, nigbati nwọn pari ere ti nwọn nṣe na tan, ni awọn ti o pede are na bẹrẹ si kọrin ilu Ghana (Ghana National Anthem), ẹnikan ti ko dide nigbati nwọn nkọrin na ni awọn ọlọpa ilu Aganyin mu u wọn ki lo ṣe ti ko dide; nwọn ni o nfi orin-ilu awọn ṣe yẹyẹ.

Arufin na ni o rẹ on ni ni ko jẹ ki on le dide fun ọrọ yin na; o ni on ko bẹ lati ṣe iyaju si Ijọba.

## Oloye Akintola Ni Ijoba Yio Sanwo Awon Oba

(O bẹrẹ loju ewe keji)

ni igbẹkẹle eto Ijọba rẹ ti fọwọ sọya fun ipade awọn lọba lọba wipe gbogbo owo ijoko wọn atẹhinwa ni awọn yio san fun wọn.

Eyi jẹ ọkan pataki ninu ọrọ ti Oloye Akintọla sọ ni ipade awọn ọba na ni ijẹta. O ni on kan saara si awọn Ọba na fun suru ti wọn ni lati nkan bi oṣu mẹ je sugbọn bi ẹbi na ko nṣe lati ọdọ Ijọba on bikoṣe awọn anikanjọpọn ti nwọn ba gbogbo eto Ijọba jẹ ni ipinlẹ yi.

Oloye Akintọla ni gẹgẹbi baba si ọmọ rẹ awọn ko gbọdọ foju pa awọn ọba yi rẹ nitori baba ni jẹ fun awọn lọnakọna ati on si ro wipe nwọn ko ni fi gbogbo ẹru lati gbe eto Ijọba na de ori da awọn nikan.

Onirohin Eleti - Ọfẹ ni on gbọ wipe gbogbo owo atẹhinwa ti Ijọba yio san ni gbese fun awọn ijoye ati ọba Ipinlẹ Iwọ orun jẹ Ọkẹ mẹta-o - le - ẹgbẹrun pọnun, (£61000).


RECORDS OF THE WEEK

78 R.P.M. at 7/- each
P 82462 H
Me Begyaa M9/Ota Bebrebe Yi
P 82461 H
Oba Dzisecle/Odeyewu
Bra E. K.'s Band
P 82482 H
Nsa Fufue/Nahoma Tea
Casino Dance Band
45 R P M at 6/9 each
P 382370 F
Kelewele/Anyi Di Eddy
Okonta and his Jolabro
Star Aces
P 382305 F
Erora/Alamie
Adeolu and his Rio Lindo
Orchestra.

PHILIPS
of course...
—the records of the century—


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street Lagos Box 467
Phone 23370 Editor, (Olotu) Ola Onatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.